**Akiyesi**

A nfẹ awọn ti nwọn ti yio ma ba wa ta Irohin Imọle ni awọn ilu wọnyi: Igbo-Ora Shaki Iseyin Eruwa Lalate Akure Ondo Ado- Ekiti Oṣogbo Fiditi Oyo Ẹde Ikorodu Shagamu Ilaro ati Ilọrin.

Ẹ kọwe si:-
Olootu IROHIN IMỌLẸ
16, Bamgbose Street,
Lagos.

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**Lakaye oro**

Aiye nigba, Igba laiye jẹ. Ogbon Imo ati Iiko lati fi oye fun Alaimọkan, Ọdọmọkunrin ati Ọdọmọbinrin. Ti o npọrungbẹ nipa imọ ati ironu, Kiyesi, ọmọ mi, iwọ sa fẹ otitọ ninu rẹ

VOL. VI No. 332 MONDAY JUNE 4 — JUNE 10 1962 KOBỌ MEJI (2)


# Oloye F. R. Williams pe Ijọba Apapọ lẹjọ fun ofin Pajawiri ti nwọn ṣe

## ẸJỌ NA YIO BẸRẸ LONI NINU KỌTU GANRAN L'EKO

EKO:- Loni ni ejo ti o l o y e Rotimi Williams tlse alaga fun awon Amofin nile Naijiria ti o si tun je o l u m o r a n nipa ofin fun egbe Afenifere ti a gbo pe IJỌBA TI FI OFIN PAJAWIRI MU LATI LỌ ṢATIPO NI ABẸOKUTA TI KO GBỌDỌ RIN KỌJA IBUSỌ MẸTA LỌ NI A GBỌ WIPE ẸJỌ TI O PE IJỌBA APAPỌ SI KOTU GANRAN YIO BẸRẸ NILU EKO GẸGEBI A TI GBỌ NI KIA TI IJỌBA TI ṢE OFIN PAJAWIRI LỌJỌ TUESDAY LATI FI PANA RO— gbọdiyan ti o wa ni ipinlẹ Iwọ orun ni nwọn ti lo ofin titun na fun awọn Oṣelu bi ogoji ni ipinlẹ iwọ Orun.

Lasiko rogbodiyan yi ni Oloye Rotimi ti fo lọ silu Oyinbo lati lọ fi oju kan awọn oguna gbongbo ninu ofin, ki o si to de ni Ijọba Apapọ tiṣe ofin pajawiri, gẹrẹ ti o de ni o ba y a r a lọ pe Ijọba lẹjọ si Kotu, ibiti o ti nsọ eyi ni o gbọ pe awọn Ọlopa ti nwa. Ni o ba ranṣẹ si Oga Ọlọpa pe, on gbọ pe o ti n wa on, bi o ba fẹ ri on ki o wa ba on ni Kọtu Ganran yio ri on nibẹ.

Ko pẹ lẹhin na ni Ọga Ọlọpa k a n de o si fi iwe A s ẹ ti Dokita Majẹkodunmi tiṣe Alaṣẹ Ipinlẹ Iwọ O run ṣe han wipe ko k u r o nilu Eko, ki o lọ joko silu Abẹokuta, ko si g b ọ d ọ kuro nibẹ lọ si ibiti o kọja ibusọ mẹta.

Ni gẹrẹ ti Rotimi gba iwe aṣẹ na, werewere o lọ ṣe iwe ẹbẹ miran si Adajọ pe ki o da aṣẹ Dokita Majẹkodunmi d u r o ati pe ko lẹtọ lati ṣe bẹ.

Adajọ si gba pe ki a fun laye loni lati wa ro ẹjọ rẹ ki o to pada lọ si Abẹokuta.



**Oloye R. Williams**

## Ijọba ko gba ki Dingle Foot duro nilẹ Naijiria

A gbọ wipe awọn Agbẹjọro meji ti Oloye Rotimi Williams mu wa lati ilu oyinbo lati wa ba gbẹjọ ti o pe ijọba Apapọ nipa ofin pajawiri ti nwọn ṣe ni Ijọba ti da nwọn pada pe nwọn ko gbọdọ duro nilẹ Naijiria ṣugbọn lẹhin ẹbẹ wọn, nwọn gba ki nwọn duro titi di ọjọ alaruba ki nwọn to pada silu nwọn, ṣugbọn a ko gbọ idi ti nwọn ko fi jẹki wọn duro nilẹ Naijiria.

Orukọ awọn Agbẹjọro na ni nwọnyi: Ọgbẹni Dingle Foot, Q. C. ati Ọgbẹni George Colthorpe ẹniti o ga ju ninu awọn agbẹjọro ilẹ Gẹẹsi.


ADVERTISEMENT NO. 76.

## KERE O

OFIN TI A NFI NA OWO ATIJO (WEST AFRICAN CURRENCY BOARD NOTES & COINS) DI PI PARE

A fẹ lati ran gbogbo ẹnyin enia leti wipe lati ọjọ kini oṣu July, 1962 (oṣu keje ọdun yi) gbogbo owo Atijọ patapata eyi ni owo Pepa ati owo Ṣile titi de ori Epini yio kuro. A ko ni le lo wọn gẹgẹ bi Ofin ni ilẹ Naijiria.

Eyi ni wipe lati ọjọ kini oṣu keje (July) ọdun yi, owo Atijọ wọnyi koni wulo fun sisan owo fun Iṣẹ Aje ni jake jado ilẹ Naijiria - fun apejuwe, aikoni gba fun Ọja rira tabi fun Ọja tita ninu Ọja ati Ṣọbu.

Gbogbo ẹniti o ba ni owo Atijọ wọnyi lọwọ tabi ni ipamọ yala ni pepa tabi ni Ṣile ni lati tara lọ ṣe paṣi parọ owo wọnyi ni Bank ki Bank fun owo titun eyiti C e n t r a l Bank ti Naijiria fi sita ni nkan bi ọdun kẹta sẹhin, ti a si na lọwọlọwọ yi ki ọjọ kini oṣu keje ọdun yi (July) to to. Ọfẹ ni gbogbo Bank yio parọ owo wọnyi fun yin.

*JOHN BEACH*
*Deputy General Manager.*

*Central Bank of Nigeria,*
*Lagos.*

## Waya Ina Lẹntiriki pa Ẹlẹmu kan lori Kẹkẹ

*YABA:- Lotu Ọjọ kan ti ojo rọ aromọju ni Ọkunrin Ẹlẹmu kan ti o njẹ Sedu gbe Kẹkẹ rẹ ni idaji pẹlu Keregbe o si kọri si ọna Onikẹ lulmọ wipe waya onina kan ti ja didu ọna. Bi o ti nsare lọ wipe ki on tete de oko ẹmu rẹ ni kutukutu owurọ, bẹni o kan Waya ti o dubu oju-ọna na. Bi o ti ko bireki (Break) nṣe lo kuku lọ fi ọrun kọ Waya Afikupani yi, Waya si gbe ati on ati Kẹkẹ ati Keregbe rẹ ju sinu Igbo.*

*Nwọn sare gbe lọ sile alaisan ni Yaba, Dokita ti o mbẹ lẹnu iṣẹ ni akoko na, du ẹmi Ẹlẹmu na fun igba diẹ sugbọn ọpa ko ba oro mọ. Bayi ni SEDU Ẹlẹmu yi ti o jẹ ọmọ SANMỌRRA ni Ilẹ-IGBOMINA ba ku iku Oro bumu-bamu.*

*KI OLUWA KIO FI ORIJIN O!*

## Awọn Alaṣẹ Okere fun ilẹ Afirika ṣe Ipade nilu Eko

EKO:- Awọn Alaṣẹ ilẹ Okere ni erekuṣu ilẹ Afirika ati erekuṣu Madagaska ti nwọn ṣe ipade nilẹ Naijiria ni ibẹrẹ ọdun ni, tun pade pọ ṣepade miran nilu Eko lati jumọ jiroro bi ilẹ wa yio ṣe dara siwaju ti alafia yio si gbilẹ ni ilẹ na.



**Ọlọla Jaja Wachuku**
(ALASE OKERE FUN ILE NAIJIRIA)

Ofin mẹtadinladọta ni nwọn ṣe fun ilọsiwaju ilẹ Afirika ati Malagasy, ati pe gbogbo awọn to ṣe ofin nwọnyi jẹ Aṣoju Ijọba kọkan Ipinnu ẹgbẹ yi ni wipe ki a yan ẹnikan ti yio ma ṣe aṣoju bi owo nina ti nlọ si ni Ipinlẹ ati ni agbegbe kọkan, ẹnikan lati maṣe Alabojuto bi owo ti nwọle si, ẹnikan lati ma ṣe ofin toto, bi alafia ti ngbilẹ si, ẹnikan lati ma ṣe bi iwadi bi Ilọsiwaju ninu ẹkọ ti ngbilẹ si, ẹnikan ni lati ma ṣe itọju awọn ohun Iṣẹdalẹ wa, ẹnikan lati ri daju pe ko si Idana ninu ọrọ sisọ si ara ẹni, ki a si maṣe Ikede si ara ẹni, ki asi ma gbọ Irohin ara ẹni, ki a ma ba ara wa ṣiṣẹ papọ, ki a si ni Ajumọṣe

Ọgbẹni Jaja Wachuku tiṣe Alaṣẹ Ilu Okere fun ilẹ Naijiria ni nwọn yan ni Alaga Ipade na.

# Yẹyẹnatu!

## O NI YẸYẸ EKO

Olotu:— Halo! Yẹyẹ, Ẹku rogbodiyan ilẹ yi.

Yẹyẹnatu:— Rogbo wo lo diyan fun yin? Ẹ yago fun mi o jare, ohun kuku nṣalarun ko ṣẹlẹrin

Olotu:— Kini yen kẹ, Haha! Yẹyẹnatu o ma sirọsi kẹ?

Yẹyẹnatu:— Mo nsọ fun yin ẹ ba mi sọ fun Ọkọ mi ko jẹki ori rẹ fapo

Olotu:— Ko ri rẹ fapo bi ti mọto? To ba faa ẹe wa laiki rẹ?

Yẹyẹnatu:— Ṣe ẹnyin laiki ibi to nṣiṣẹ yẹn?

Olotu:— Hẹn, ṣe bi I w ọ na ni o jẹ ko kuro nibito wa tẹlẹ.

Yẹyẹnatu:— Nibo lo wa tẹlẹ?

Olotu:— Ha-ha, Ṣe bi ẹba l ọ k ọ rẹ nta tẹlẹ

Yẹyẹnatu:— Hẹn, ẹnyin gbọ B a b a ọlẹba ri ni? Ẹ sa ba sọrọ ko jẹ kori on pe.



Olotu:— O dara ni bo lo ti nṣiṣẹ nisisiyi ti o ko fẹ?

Yẹyẹnatu:— L'agege ni kẹ

Olotu:— Ha-ha, Ṣe Agege yẹn ko wa dara ni?

Yẹyẹnatu:— Ṣe ẹnyin lẹ ṣiṣẹ nibẹ?

Olotu:— H ọ w u! kini ṣe, ko si ibiti nko le ṣiṣẹ.

Yẹyẹnatu:— Bẹna ni

Olotu:— O si da mi loju pe Iyawo ko jẹ binu pe, ko da ki nlọ ṣiṣẹ ni Ibadan

Yẹyẹnatu:— Ko buru, ọjọ ti nba tun ri i ninu Agege ṣa, ma wọ bọ silẹ ni

Olotu:— Hẹn, ko yara mura toju owo bọsi to ma ma wọ lọ ni yẹn

Yẹyẹnatu:— Nwọn figba iwaju ile wa kọja kẹ.

Olotu:— Awọn wo?

Yẹyẹnatu:— Awọn Agege

Olotu:— Awọn A g e g e ngba iwaju ile yin kọja? ọrọ rẹ ko ye mi mọ

Yẹyẹnatu:— Ha-hẹn, ẹ ko mọ ohun ti a npe l'Agege nisiyi.

Olotu:— Ki iṣe Agege ikọja Oṣodi.

Yẹyẹnatu:— Ha! ha! ha! Abajọ ẹ lẹ fẹ ṣiṣẹ ninu Agege Mọto agbe igbẹ ti taun kansulu nlo lo njẹ Agege kẹ.

Olotu:— Ha! Nko ṣiṣẹ ninu Agege o Ha! ma bọkọ rẹ sọrọ ko yara kuro ninu Agege Haba on to sanra to yẹn, ko mọ pe ti on ba ku on yio wu pupọ ju, a ko ni nawo Posi nla ni

Yẹyẹnatu:- Ko mọ iwọn ara rẹ ni

Olotu:- O wọn ara rẹ ni ana ni Kinsiwe kẹ, tabi ko fi han rẹ.

Yẹyẹnatu:- Ṣe ẹnyin na si ti wọn ara yin?

Olotu:- Nko raye de Kinsiwẹ.

Yẹyẹnatu:- Haba ẹnyin lẹ ko mọ iwọn ara nyin ninu iyẹn kẹ.

AWOLỌWỌ SO PE:-

## Balewa ti di ẹniti o nṣe Ijọba bo tifẹ

EKO:- Oloye Awolọwọ sọ pe Alhaji Tafa Balewa ko tilẹ gbọ sisun, ko gbọ fẹju nṣe lo nkan nṣe Ijọba bo ti wu u ko si fẹ ki ẹnikan tako on, o sọ wipe, iru iwa ti oloye S. L. Akintọla fẹ ma hu ti Ijọba Iwọ-Orun ko gba fun, ki o to wa di pe ba-a-jẹ ni nwọn fi ṣe.

Lẹhin ti Oloye Awolọwọ ti nṣe Irohin gbogbo iwa ti Akintọla hu larin Ẹ g b ẹ Ọlọpẹ, atilẹ abọ ninu ọrọ agbọsọ wipe, on li ẹni ti o se e s u beleke lẹhin Ologbe Ikoli ni akoko igba ti o nṣe Olotu iwe Irohin Service, tobẹ ti Ọkunrin na sọ pe nkan ti Akintọla ṣe fun on yi, on ko ni gbagbe titi ko da ki on ku on yio ma ranti ri ninu Iboji.

Oloye Awolọwọ s ọ p e, ọdun mẹjọ ni on fi se Premier nigboro ilu Ibadan ti on ko fi ọwọ gun, ti on ko jẹ gbese, ọkọ Ọba ko ṣi on lẹsẹ, bẹni ọdunrun ọkẹ pọnun ri on fi s i l ẹ. On ko jijadu lati tun padu si Ibadan. Ṣugbọn on fi Alhaji Adegbenro ti iṣe ọmọ Musulumi si ipo Akintọla.

# IFẸ LOJU

## (APA KẸJỌ)

Mo bẹ gbogbo ẹnyin Ọnkawe Irohin Imọlẹ pe ki ẹ maṣe binu wipe ẹ ko ri apa Kẹjọ Itan mi ka ni ọsẹ to kọja aiko ri aye to ni ko jẹki a kọ ṣugbọn loni ẹ o ka apa kẹjọ na ni kikun.

Mo ro pe gbogbo yin ni o mọ ibiti mo ba Itan na de ni ọsẹ keji sẹhin. Eyi ni ibiti Muli ko fẹ lati ṣe Iya rẹ mọ, nitorina o kọ lati gbọ ọrọ si i lẹnu, Ojogẹ ko si ni owo lọwọ to bẹ ti yio fun Muli, nitorina kosi Alafia larin wọn.

Ṣe ọgọrọ Iya li o nti ọmọ wọ Igbe, aimọye Iya lo nsọ ọmọ d'oloriburuku. Ifẹ Muli ko kuro lọkan Ojogẹ bẹni ti Ojogẹ ko dinku lọkan Iya Bọlaji, Iya Muli ni lusifa ti o ko si tọkọ taya larin, ti ko jẹ ki wọn tun gbadun ara wọn.

LATI ỌWỌ:—

Afolabi Ọlabimtan

Ni otitọ o yẹ ki Ọmọbinrin ma ni olumọran bi Iya ṣugbọn bawo ni iba si tun ma dun to bi ọpọlọpọ Ọmọbinrin ba le ma gbe Imọran si ori iwọn, ki nwọn ma ranti pe Alatiṣe ni o nmo atiṣe rẹ, ati pe bi o ba buru tan ti awọn nikan li yio da.

Nigbati gbogbo nkan nwọnyi nlọ bayi Ojogẹ pe Akin Ọrẹ rẹ o fi gbogbo ọrọ na han, O ni "Akin, lati ọjọ ti emi pẹlu rẹ ti wa, o mọ wipe ko si ohun kan ti mo ma nfi bo fun ọ, ati ninu gbogbo ọrẹ ti mo ni ọtọ ni aye ti o wa lọdọ mi Se iranti wipe lati ọjọ ti mo ti fẹ Iya Bọlaji nko mu ọrọ rẹ de iwaju rẹ ri. Nitori eyi, fi ara balẹ ki o gbọ ohun ti ngo sọ fun ọ yi, O dakẹ diẹ, fun iṣeju meji ko le soro, nitori ọkan rẹ wuwo; Ibanujẹ ru lati inu ọkan rẹ wa, o si fi ara rẹ balẹ diẹ ki o to bẹrẹ si soro, Ọkunrin ṣa ni, o si gbọdọ ṣe Ọkunrin. Akin ri wipe ko bẹrẹ ọrọ, o dahun o ni kini o de, Ojogẹ soro "O si bẹrẹ ọrọ rẹ o ni lati igbati Ana mi ti nwale wa, ni Iyawo mi ti bẹrẹ iwa aika enia si, ko bikita fun mi mọ Iya rẹ ni o si nkọ si mi.

Mo kọkọ nfi ara da a, mo si fi ṣi Iyawo mi leti pe ki o ṣe akiyesi pe Iwa rẹ nyatọ si ti atẹhin wa ati pe ti ko ba pada sibi ti atijọ, emi na yio yi Iwa pada. Mo fi eyi halẹ mọ Iya Bọlaji, ṣugbọn sibẹsibẹ Iya rẹ nki i lọkan, o si nrangan si mi. Ni aipẹ yi Ana mi pe mi o si gba mi ni Imọran pe, ki nfun Iya Bọlaji ni owo ki o fi sile Itaja nla ti yio ma joko dipo ko ma gba Ọja kiri ile Itaja Oyinbo.

Mo si da Ana mi lohun pe owo pọ lowọ mi, ṣugbọn bi Iya Bọlaji ba le ma gba ọja bo ṣe ngba tẹlẹ, to ba si nṣoju ere rẹ, ni aipẹ ọjọ ngo ko iwọnba owo ti mba kojọ silẹ a o si fi ṣi Ile-Itaja na. Eyi ko dun mọ Ana mi ninu o si leri pe ni iwọn igbati nko ba ti ṣe oh... ti on ..., o ko si jẹ ki ọmọ on ṣe ohunkohun, nitoripe ọmọ oti Ọla ni.

Nitotọ lati Igbana ni Iya Bọlaji ti kọ lati gba ọja lati ọdọ Oyinbo, nko si jẹ kini kan loju rẹ mọ, Nisisiyi ọrọ na wa pin mi lẹni nko si mọ ohun ti ngo ṣe mọ, fungba diẹ lẹhin ti Ojogẹ sọrọ tan, ọrẹ rẹ ko mọ ohun ti on sọ mọ, ṣugbọn nigbati o pẹ, o dahun o ni, "Ọrẹ mi Oluwa to da Iwọ ati Iyawo re pọ, ko ni ya nyin" Olodunmare yio da ọmọ si fun nyin, Ojogẹ sare dahun oni, ki Ọlorun wo wọn pọ, Akin si tun nba ọrọ re lọ, Ọba Oke yio si jẹki a rẹrẹ ara wa. O ku suru, Suru Baba iwa, bẹni nwọn wi, hẹn, ṣugbọn Suru na ko gbọdọ tan, ọrọ to wa nilẹ yi ko tọ ki o tan ọ ni suru. Ati mọ ara wa pẹ, mo si lero pe ohun to ba ba oju, ọrọ ni ki o ba Inu, mo si Ifẹ Iya Bọlaji ju gbogbo ohun ti o nṣẹlẹ yi lọ, ṣugbọn o yọ ka mọ pe ti ko ba nidi ada ko ni da lasan. Eku ẹda lo wọle to si da eyi silẹ

Imọran ti emi nisisiyi ni wipe ki a pe Sikira, ọrẹ Iya Bọlaji, ki o fi ọrọ wọ ọrọ lẹnu rẹ ti o ba ni ọwọ si ohun ti iya Muli nṣe. Ti ko ba ni ọwọ ninu rẹ, emi gẹgẹbi ọrẹ rẹ, on gẹgẹbi ọrẹ Muli, yio pe ẹnyin mejeji si ijoko ao si ba nyin sọrọ.

Ti o ba ni ọwọ si imọran mi yi ngo ranṣẹ si Sikira. Tabi kini o wi? Ojogẹ si dahun o ni on fi ọwọ si ọna ti ọrẹ on fẹ gba.

Nigbati o di ọjọ keji Akin lọ si ile Sikira, o si ba on pẹlu ọkọ rẹ nile. Nwọn fun ni ijoko, o joko o si bẹrẹsi ba wọn sọ orisirisi ọrọ Bi ọmọ Sikira ṣi ti na ọwọ, ti o mu iwe kan lori ibuṣun, iya rẹ ja gba lọwọ rẹ, ọmọ na si bẹrẹ si ke, Akin fa-amọra, o bẹ-ẹ, o si pa ẹnu mọ ni ikẹhin Akin wa dahun o ni, "Ninu ọmọ rẹ ati Bọlaji ọmọ Muli ti tani o ntilẹ nyọmu ju?"

Sikira dahun o ni "Ha, nko le sọ ṣugbọn Jide nfoju mi ri nkan, ati pe emi, n gba pupọ si ni. Ṣugbọn Ọlọrun ba ọrẹ mi se iya rẹ nran lọwọ" Inu Akin dun pupọ pe Sikira sọ ọrọ nipa iya Muli o si yara dahun o ni 'Nitotọ ni o, Iya Muli nṣe o, tabi iwọ na ko ri pe iyatọ de nigbati Iya muli bẹrẹ si wa sile ọkọ rẹ?' Ẹ ma ṣe o, burọda Akin, nko mọ pe ẹnyin na nṣe akiyesi. Sikira ni, mo ri wipe iwa tọkọtaya wọn ko tun ri bi ti atijọ, ọrẹ mi ko sọ ohunkohun fun mi. Tabi ẹ mọ ti awọ ba wa larin wọn ni

Ohun ti Akin nwa gan ni eyi. Inu rẹ dun pupọ, o si da Sikira lohun o ni o pẹlu ohun ti mo ṣe wa ri ọ. Ṣugbọn ki nma purọ fun ọ, ija ni mo lẹ kọkọ fẹ ba ọ ja bikoṣe ohun ti ọ sọ fun mi tan yi, nitoripe emi ro wipe o mọ gbogbo ohun ti o nlọ, o ko si ṣe ohunkohun si. Ṣugbọn nisisiyi, mo mọ daju pe o ko mọ ohunkohun Ija si pari. Ni ana ni ọrẹ mi pe mi ti o sọ gbogbo ohun ti o ṣẹlẹ fun mi, Akin si to gbogbo ohun ti Ojogẹ sọ fun Sikira, o ni, ṣugbọn nigbati o pari gbogbo rẹ mo sọ fun pe ngo ri ọ loni ngo si sọ ohun ti mba ro fun. nisi-

WO IYOKU NI EWE KARUN

## Ẹgbẹ Ansarudeen fi ẹbun ta Durosimi Etti Lọrẹ



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ti o rọ fila Gọbi ti o si wọ ẹwu Daṣiki funfun ni Ọgbẹni F. A. Durosimi Ẹtti nigbati Iya suna ẹgbẹ Ansarudeen Alakoro nfi ẹbun ta Ọgbẹni na lọrẹ fun mimọ riri iṣẹ rẹ gẹgẹbi ẹkan ninu Olukọ.

O BẸRẸ NI OJU EWE KẸRIN

ẹiyi kini o ropc a le se ọrọ na gẹgẹ bi ọrẹ tọkọtaya wọn .Sikira dahun o ni "He-ẹ, tabi iru kini eyi papa. Kini awọn Iya wa nṣe bayi fun? bẹni ọrẹ mi ko sọ ohunkohun fun mi, boya o mọ pe nko ni fẹ iru iwa bẹ ni. O mọ po Iya on ko fẹ ki on komọ pe o fẹ tọ mi ṣọna ti ngo ti ri ibinu ọkọ mi ti yio si fi fi mi silẹ ni. Ngo ranṣẹ si Muli ngo si mọ ohun ti ngo ba sọ, tabi kini ero burọda Akin? Akin si dahun o ni Baba Jide e ṣa gbo gbogbo ọrọ na, nwọn ni bi ọmọde ba laṣọ bi ti agba kole ni akiṣa to agba, toto o se bi owe, ẹ ba wa sọ si Ọkọ Sikira si dahun o wipe agba ki wa nilu ki orọmọ tuntun pa, ajulumọ ko gbọdọ jẹ ki ohun ṣun igbẹ; ẹ mura ẹnyin mejeji ki ẹ mọ bi ẹo se ba tọtun-tosi wọn ṣọrọ ti ọrọ yi yio fi yanju.

Nitoripe bi o ṣe nlọ yi, ẹ sọpe ọkọ Iyawo ni on ko ti ni owo to lati fi sile itaja, bẹni ana si fi ake kori pe ọmọ on ko gbọdọ gbọ tirẹ mọ titi yio fi si Ile-Itaja fun-un, Ọlọrun nikan lo mọ ibiti yio pari si. Adura ki ọrọ yi ma ya wọn ni kia ma gba. Ki Oluwa si da ọmọ si fun gbogbo wa"

Akin dahun o ni, ẹ ṣe pupọ, ki Oluwa ṣe agba lanfani, Iya Jide ngo ranṣẹ si Muli pe ki o wa sile mi ni irọlẹ ọla ni dede agogo marun ngo sọ fun Ojogẹ papa pe ko wa, yio si wun mi pupọ to ba le wa sile mi nigba yẹn. A, hẹn, mo tọrọ gafara si lọwọ baba Jide o. Baba Jide si dahun o ni kini yẹn kẹ? Bayi ni Tọkọ-taya mejeji ṣe fi ohun ṣọkan lati gbiyanju lati lo ile ọrẹ wọn ti Iya Muli fẹ wo.

# Owo Iranlọ-wọ fun awọn ẹgbẹ Scout di ẹgbaa marun

Awọn Irohin lati ile Jẹẹ awọn ẹgbẹ Scouts ati Guides pe Iranlọwọ owo ti wọn da silẹ ni eṣi fun Ilọsiwaju ẹgbẹ Scout ati Guides lati ọwọ Gomin Agba labẹ Alaga Ọgbẹni Denis Ọsadebay ti pọ to ẹgba a marun £10 350.

Eniti o kọkọ da owo na ni Ọlọla Dọkita Nnamdi Asikiwe tiṣe Gomina Agba fun Ilẹ Naijiria, o da ẹgbẹrun Pọun, ẹniti o tun ṣe bi tirẹ ni awọn Oyinbo U. A. C. nwọn da ẹgberun Pọun £1000 owo nyin yio ma re oke o.

# Ẹ ma ka Irohin Imọlẹ ni gba gbogbo

# Awọn ọmọ Musulumi to nkirun nilu Oyinbo



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni awọn ọmọ Musulumi ti o lọ kọ ẹkọ nilu Oyinbo ni a nwo nigbati nwọn nkirun ọdun Ileya ni adugbo kan ti nwọn npe ni Woking, Iwọnyi ni awọn iṣẹ ti nwọn lọ kọ Law, Doctor, Machinist, Technology Biology, Chemist, Specialist ati bẹbọ, Awọn ... lo wa ni ẹhin, ni ẹhinkule Mọṣalaṣi Woking ni nwọn gbe kirun na.

# AKA BẸRIN DE O

Lati ọwọ:- Ọmọ Ẹgbẹ Imọle Aiye No 443
MURITALA AZEEZ

Ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ ẹ gba eloyi yọwo o! ni ọjọ atini ti iṣe ọjọ monday ọjọ kẹrin larin oṣu karun ọdun yi ni mo ri enmọ nla kan ni Bariga gbogbo wa la mọ wipe siso n a nso ẹran Ileya mọlẹ ni itagbangba.
Ṣugbọn baba kan ni o so ẹran Ileya rẹ mọlẹ ti o si gbabẹ de ẹrun baba na so ẹran rẹ mọlẹ lai mọ pe okun ti on fi so ko lagbara baba na gbe awọ ikirun jade si iwaju ẹran na lati kirun ṣugbọn bi baba na ti roku ki o gbe ori soke ni ẹran rẹ ro wipe o nle ọwọ ija si on ni paka ti ẹran yi ja ni o ba kan baba na ni iwo bẹni baba ba fi idi jalẹ ti o si gbabẹ de ọrun o!
Edunmare jare maje ki a fi ọwọ wa ra iku wale o! (Amin).

# Awọn Ọmọ Ilẹ Nigeria nlọ kọ ẹkọ nilẹ Jamani

Lojo Monday 28th osu May 1962 ni awon enia mokandinladota ninu awon omo ile Nigeria yio ba oko ofurufu ti nwọn npe ni Lufthanse kuro ni Ikeja lo si odo Ijoba Alapapo se nile Jamani lati lo ko eko Ọlọfe.

Awon merinla ninu won yio lo ko isẹ elero tabi ise owo merinla miran ti yio tele yio lo ko ise bi a ti nse jigin Aso ati bi a ti nse o ogun die ninu won yio lo fun ise nwonyi Biology, Astronomy, Pilot, Technology, Forestry, Civil Engineer, Steam Engishe Mechanistation.
B. C. Achlike, A. Ofegbe, B S Olusegun, E B Ncanga C C Ngwu, C M Ukome, J B Ihenacho, G A Igo D O Tioboro, P C O Uduh, G A Sadjere, M O Adewakun, F I Okere, F O Osahon, J K Kubeyinje C E Amadi, J M Adu, O S Akapo, C O U Duru A K F Olaleye, G Ikajuangbe, O J A Esseen, P Ch Egbun, I O Okitikpi, K J E Mononye, P A Chukwu P N O Akoje, I U Igormu. James Adebayo, A Lajorin S E Ngonebu, D G Enoghene, A Oluwole, J O C Nwoji, E I Oßieya, Y A Jinoh, G G Chinawa, W E Adodo, Ch K Dokubo, S C Nwuchuku, J E Olumese, O Adeniyi O E Osundu, G Ikihmi, S O Oyegun U O O Mba, W P Uti, S C Ilodubah S A Bola.

# Awọn ẹiyẹ Ilẹ Nigeria nfo de Ilẹ Rọsia ati Ilu Oyinbo

Awọn oyinbo kan wa ni ile Nigeria ti nwon nse iwadi wo kakiri boya eiye ile yi nfo de ilu miran li oke okun nitorina nwọn ko awọn eiye ile Nigeria jo nwon si fi oruka ati nomba si wọn lese lehin na nwon se ikede kakiri aiye wipe enikeni ti o ba pa okan ninu awon eiye nwonyi ki o ja nomba ese re ki o si fi ranse si ogbeni R E Sharland Jos Museum P. O. Box 791 Kano Nigeria

Awon eiye nlanla ti nwon fi oruka si lese ti nwon si jeki uwon fo lo awonyi je 1034 lati igboro Kano o dabi enipe awon eiye wonyi ko le fo koja ile Italy nitoripe nwọn pa meji rẹni aroko San Benedetto nwọn si tun pa ọkan ni ilẹ Malta.
Awọn ẹgbẹ ti o nṣe itọju awọn ẹranko nilẹ Kalaba ti fi oruka ti o ni nọmba si ẹsẹ ẹiyẹ Alatandẹdẹ lati mọ bi nwọn ba nde Ilu Oyinbo nwọn pa mẹta rẹ nilẹ oyinbo meji ni Ilẹ Faranse ati ọkan nilu Payan.

Nwọn ti nṣe iru nkan nilẹ Gẹsi ati Amerika fun ọjọ pipẹ o di ẹiyẹ mẹfa ti wọn pa nilẹ Nigeria ninu awọn ẹiyẹ ti nwọn fi oruka si lẹsẹ bẹ lati Ilẹ Amẹrika ati Rọsia.

# NIHIN LOHUN ATI NIBI GBOGBO

LATI OWO:- AJEGBORODAGBA

## HA!, BI E PE NMA WI EYI, MA WI, OMODEBINRIN OMO ILE-EKO NMU SIGA NILU EKO!

Mo de, mo ki ara ile, e ku ile; mo de, mo ki ero ona, e ma ku ati, emi oko Adija ma tun de olohun aro A ji soro ti Awoko ko to duro ti. Omo Akin ma tun de.

O ti to bi ojo meta ti mo ti soro gbehin, sugbon oro kan mbe lokan mi ti mo fe wi, aiko ri aye ni ko je, sugbon loni mo segun idiwo na nitori bi awon enti oro na ba wi ba ti ri akole mi oke yi ni awon yio ti ma fi enu gba ara awon tabi ki nwon ma bu mi.

Enyin omodebinrin e je ki ori yin fa epo gegebi asa ti e nda lode oni, eyi ni pe ki e sora yin, e yo mu Siga mo, Siga ko dara aran buruku ni o nfa, o ti to bi ojo meta ti mo ti nri asa na lowo awon omobinrin wa nipa Siga mimu. O se lale ojo kan nigbati mo jeun yo tan ni mo ba pe Adija yawo mi nao ni ko jeki a lo wo aworan ale eyini Cinema, bi ogon a gbe'ra o di ohun. Nigbati a wo ile tan ni a ba joko, gegebi enyin na ti mo mi pe emi ko lo si Cinima lasan bi ko se l a t i ri ohun so fun yin ni. Ko ju iseju marun lo ti a wole ni ere ti po.

Bi mo ti nwo fofo ni mo taju ri omodekunrin kan ti ko gaju ese Bata meta lo ti o si mu omobinrin kan dani bi nwon ti wo'e tan, iwaju emi Jagunlabi ni nwon joko si, ni omodekunrin yi ba yo Siga lapo o si fun omobinrin na ni okan, on na si mu okan ofi si enu ni omodebinrin yi ba so ina si tire, o si tun sana si ti oko re pelu. Ha! mo lanu nigbati mo ri, emi ko si le pade mo titi ti mo fi wo ile mi nitori o ya mi lenu pupo, n i t o r i omode ni awon mejeji o si da mi loju nwon si nlo si Ile-Eko ati pe nwo wa lonu bi bo ni.

Iru asa bayi ko ma dara, bi o ba tie nri owo awon obi re ji, kini se ti o ko fi ra aso Siga re, tabi kio ma fi pa mo nitori Igba ki nlo bi orere, A i y e ki nrun bi opa ibon ti o ti iwoyi lo gbe Siga mimu dani.

Ha! Iwo Omode birin ti o nmu siga aru mi se o, nitori o ko mo pe arunburuku ni Siga mimu nfa si enia lara ni, tabi o fe so arare di arugbo osan gangan jowo lo fi siga mimu sile ko dara fun omo ile eko o nma mu enia gbagbe nkan ti nwon ba nko ati iwo omodekunrin papa E jowo e fi siga mimu sile ko dara enyin omodebinrin t a b i ise asewo ni e nfe ma se ni.

# ASA IBILE YORUBA

LATI OWO:- BILLIAMINU BALOGUN ALLI
No. 372 OMO EGBE IMOLE AIYE

### 1 A KI DUPE LOWO ASEKU

A nlo ede yi lati fi gba enia ni iyanju ki o le se asepari ore. Agba tan ni a ngba Ole, bi a ba da aso fun tan, a si pa a laro.

### 2 NKA ESE IYAWO

Iyawo ti a ba sese gbe, ko naare rin, nitori bi a ba ri enti o nrin gbere, ao wipe eleyi nka ese iyawo.

### 3 ANILE NI PEREGUN NNI ASO

A ma nlo gbolohun oro yi lati fi nore fun enia iyen ni pe pupo-pupo ni nao ohunare yio ma pe siwaju gegebi Peregun ti nle si, iyuku di igbamiran.

BERE OJULOWO EGBOGI AWON FARANSE TI A NPE NI:-

## "UROXAL"



Fun Itoju tabi fifo Apo Ile Ito Kidney-Bladder fun Okunrin ati Obinrin bi awon amodi wonyi ba nyo o lenu Ehin didun eri ile ito tabi ito-jijo enu, ito tirun, rukuruku Pipon tirun, lakuregbe, ibadi wiwo, erunkun, owo, ese. Ejika wiwu tabi riro.

Ara sisan, titobiju aiko le gbe ara konkon tabi kiakia didide loru nigbakugba, ati orisirisi awon aisan tabi amodi ba wonyi ni egbogi yio bidan ni yio wo san lara re ni kia kia ti alafia yio si de si o. Meji re kosi ni ilu Naijiria nitorina sora ki awon eleru tabi awon Oni robirobi ma ta orisi miran ti ko ni lari fun e, mase gba a rara o! Owo re je Sile Mejo abo 8/6d owo Oko Sile meji abo (2/6d). Bere Egbogi yi ni sobu awon Saro ti won npe ni:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET YABA

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET OSHOGBO

ATI NI SOBU IBADAN:-
ISE OLODUMARE DISPENSARY OKE-BOLA

# YE IRAWO RE WO

Enikeni ti o ba nfe mo kini odu irawo ti o sese jade fun on gegebi asotele osose ki o wo eyiti o ba, ba ojo ibi re mu awon asotele na ni wonyi:-

Jan 22 – Feb 20 (Aquarius) Nkan ko ni dan fun o ni ojoro ojo kan ninu ose yi, Iwo yio si ma kanra ni esan ojona gbogbo ojo na ko ni be suo fun o.

Feb 21 – Mar 20 (Pisces) Iwo yio rin irin ajo kan, ti iwo ko lero re tele. Irawo re yio tan gidigidi ninu irin ajo na.

Mar 21 – Apl 20 (Aries) Eso di owo re, mase gba eko keko. Bi enikan ba pe o mase dahun.

Apl 21 May 20 (Taurus) Irawo re yio fi ona han o gbogbo nkan re ti o diru yio di daradara

May 21 – June 21 (Gemini) Loju re sile ki o ri nkan ti ori re yio se fun o iwo yio ri nkan nsare kan.

June 22 – July 23 (Cancer) Iwo yio ba enikan soro owo owo na yio si te o lowo ninu ose.

July 24 – Aug 22 (Leo) Gbogbo ohun ti o lero pe iwo fe se larin ose yi ko ni bo si mu ero buruku kuro ni okan re.
ki o ma ba fi enu re daran.

Aug 23 Sept 23 (Virgo) Sora re pelu e ebu larin ose yi ki o ma ba fi enu re daran

Sept 24 – Oct 23 (Libra) Asiri awon ota re yio tu jade fun o ri nigbana iwo yio mo e n i t i o feran re

Oct 24 – Nov 22 (Scorpio) Lo re ara re sile lose yi ki o ma ba je obe ti iwo ko se sugbon iwo gbo Irohin ayo kan lati odo enikan ti o feran re.

Nov 23 – Dec 22 (Sagittarius) Mase jafara lati rin sun mo ojulumo re kan ti o nse o lore ti ko jeki o mo wa.

Dec 23 – Jan 21 (Capricorn) Se gbogbo ejo oni lojo isimi mase fa iti beni mase fa ijogbon.

# Abọdẹrin Ninu Igbo Maperan (Apa Keje)

LATI ỌWỌ ABUDULLAHI A. AWẸLẸNJẸ
No. 1, ỌMỌ ẸGBẸ IMOLẸ AIYE

Nibiti mo ba itan mi na de ni:- Nigbati o ku ọjọ keji ni a ti kọ arawa ni ohun ti ao ṣe, ohun ti a si fẹ ṣe na ni kia fi arawa silẹ fun iku nitoripe awa ni a fa ọran ti ọran si tọ wa wa, ti a gbe ọmọ Ekun loju iya iya rẹ ti a ṣalọ, ti a da omi gbigbona le arawa lori ki Ọlọrun ma jẹ kio yi wa lọwọ o.

Ni ọjọ kẹta, laro kutu h a i ni nwọn ti mu wa lọ si arin ọja ti nwọn si de wa tọwọtẹsẹ, nigbati o se nwọn bẹrẹsi nwọ de lati wa wo iran wa, ibiti nwọn si de wa mọ jina diẹ si ibiti awọn e r o iworan wa, nigbati o se Ọba wọn gun enia de, o gun wa pẹlu enia rẹ, bi a ti ri eyi a bẹrẹsi pe ọfọ kikankikan, ọfọ ti Abẹṣin bi oke ni o si kọkọ jẹ, were ni idẹkun de ba wa ti ẹnikẹni ninu ko funra si wa, Olohuniyọ p a p a na ti di ominira lasiko yi a joko a bẹrẹsi nworan, nigbati o ṣe awọn Apania de, mẹrin ni wọn oju wọn si pọn koko nwọn tobi, nwọn si dabi Inaki, nwọn mu ọbẹ aṣoro dani nwọn mbọ lọdọ wa, awọn Ọba na nwo bi ao ti ṣe ku, a si ti sọ fun arawa, ohun ti ao ṣe, bi nwọn ti nsun mọ wa bẹ ni olukaluku wa ti mura de wọn.

Lairotẹlẹ a fo mọ wọn lọkọkọkan, a gba ọbẹ ọwọ wọn alu wọn; mo si pa ẹniti o doju kọ mi, ṣugbọn olohun Iyọ ko le ja, o si nṣa kiri, bi mo ti ri eyi, mo ṣare lọ sibẹ, bi Ọkunrin na si ti kọ ẹhin si mi, mo gun ni ọbẹ, o ṣubu, o si ku. Ija wa de rẹpẹtẹ, ti gbogbo ero iworan tuka oju awa na ti mun, a si nle wọn a pa pupọ ninu wọn, a si mu Ọ b a wọn, a lu ṣugbọn ko ku, a mu Adajọ wọn na pẹlu, a si lu ti gbogbo ara rẹ fi bo falafala.

Bayi ni aṣẹ ti a na wọn ni anọ yagbẹ ti a si di Oluwa Ilu na Lẹhin igba di ẹ a fi Olohun iyọ jẹ Ọba ilu na a si yan Ijoye fun a kọ wọn bi a ṣe njẹ onjẹ ati bi a ti nṣe ati awọn nkan miran ,bẹbẹ.

Lẹhin Eyi afi Ilu yi silẹ a ki obinrin yi o digba, a kọri sọnọ a nlọ o ku irin ọjọ mẹta ki a de Igbo iyanu yi, ti a de ibikan bi a ti fẹ joko ti a fẹ ma jẹun ni a ri Ọkunrin arugbo kan ti o si juwọ si wa ki a wa nigbati a de ibẹ o wipe nibo ni a nlọ a wi fun o si wipe ẹnyin ko mọ pe lẹnu ọna ile Kiniun Ibẹru ni ẹ wa ẹnyin fiku ṣire bi o ti bayi o nlọ a si yara lọ ko ẹru wa a nsalọ bi a ti nlọ ni apade Kiniun yi, oni ori meji oju mẹta ẹsẹ meji ati eti mẹta, o santa, ori bọrọkọtọ, osi gbe oku agbọnrin onje bọ bi enia ni onrin, a si ma si igbaya soke bi o ba ti nlọ, bi o ti ri wa, ofi ọdọ wa ṣe ọna o mbọ.

Losẹ tombọ ẹ o gbọ bi ati ṣe ṣe fun ara wa ati ẹniti o ṣegun ara wọn.

TỌJU KỌBỌ MEJI RẸ.

---


## Ibanuje tabi Ironu re de Opin Ayo de!

BERE EGBOGI AWỌN FARANSE TI WỌN NPE NI:-

## "CORSIVERA"

Ojulowo ati Ajẹbidan Atamatase Egbogi ti a ṣe ni Pataki fun:-

"ARỌN KINIṢA TABI ARỌN LATỌNLATỌN" MEJI RẸ KOSI.

Bere lọdọ awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (oja ita Faji)**


# ERE AWIGBỌ

LATI ỌWỌ:- WAHEED R. OWOKONIRAN
No. 403, ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

O BẸRẸ LATI OJU EWE KẸTA

'Ekẹ Otosi ki ito ile lowuro'. Awọn alafẹhinti rẹ wa ku diẹ kiun to bọ ti ẹru fi mba a, ti wa pe awọn iyoku na laṣiri pe ki nwọn mura, ṣugbọn nikẹhin awọ ya awọn ọta ti lọ wi fun ọgagun wọn; nwọn si bẹrẹ si pa nwọn ni ipa ku-pa ati laibojuwọhin.

Ki nto pari ọrọ mi, emi yio fẹ ki ẹ fi eleyi se apaye ki ẹ mama ṣe AGUNLA si ọrọ ti a wọn O b i tabi Ọrẹ yin ba nsọ fun yin, ki ẹ ma ba di ẹni abuku lọdọ wọn. Olotu mo dupẹ aye ti ẹgbẹ mi, iwaju ni Ọ p a ebiti nrc si, iwaju ni ẹ o ma lọ.

---


BERE OJULOWO EGBOGI WỌNYI:-

## "Congreve Female Remedy"

Gbogbonṣe fun Itọju tabi Ajo Obinrin fun inu rirun Ibadi riro tabi gige ngbakugba ati oirṣiriṣi arun tabi amodi ti o ma nyọ Obinrin l ẹ n u ni Inu nigbakugba.

## "Collomack"

Egbogi awọn Jamani ti o dara julọ fun itanpara awọ ẹsẹ Ile Igbado ẹsẹ ti ki jẹki enia le wọ bata (Corncure) ati oriṣiriṣi arun ẹsẹ miran pẹlu ni.

## "Mackotal"

Atamatase egbogi awọn Jamani f u n oriṣiriṣi amodi "ETI" riro tabi didun fun Ọmọde ati Agbalagba bi o ti wun ki ọjọ rẹ pẹ to yio ṣe iwosan rẹ ni kiakia.

## "Meduprival"

Ojulowo egbogi awọn ara ilu Tatanbulu fun iwosa ni kiakia gbogbo amodi tabi OTUTU agbari, Igba aiya Ọna ọfun Imu tutu tabi ti o ma nsomi bi ikun nigbakugba, Kẹlẹbẹ ọna ọfun tabi agbari hiha, amurun ati oriṣiriṣi amodi miran gbogbo ti ibẹrẹ rẹ jẹ ọtutu Bere ti Ọmọde tabi agbalagba wọn yatọ nipa agbara wọn ni o

Bere ni ṣọbu:—

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria.**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.

ATI NI ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE BOLA


---

# Ọmọ Ilẹ-Nigeria mẹrin lọ kọ Ẹkọ Nilẹ Jamani

EKO:- Agbọ irohin wipe awọn ọmọ Ilẹ-Nijiria mẹrin gba ẹbun Ẹkọ-Ọfẹ lati lọ kọ ilọsiwaju ẹkọ ni ilu Frankfort-on-the-Main. Nwọn yio si nun lọ kọ Ẹkọ ni ile Gọṣọn ti o wa ni ilẹ Jamani. Awọn e ni a mẹrẹrin na yio gbera kuro ni Ikẹja lọjọ Friday 1st Oṣu June 1962 lẹẹ ọwọ ni a gbọ pe gbogbo wọn nlọ kọ. Orukọ wọn niwọnyi:-

Ọgbẹni O. C. UMESURIKE, O. GISANRIN, A. O. COLE ati Ọgbẹni J. F. ORINTUNSI

# IWI ASIKO

LATI OWO:- Afolabi Ojelabi

## Aiyekotọ

Iba Edumare, Oba laiyé,
Oba lọrun o
Iba Agbolọjọ leke oga oke
Iba Edumare asolotọ doga lawujo
Mo juba oke to jori kodo
Ti ko si yeka
Iba ele to sori kodo
Ti ke yena
Iba obiriki, Elẹri Ipin
Afinju Imalẹ ti nwewu irin
Iba Orikẹsinro Afoju agnda bina
Iba Okiki adugbo, b a b a Bọlale
Afinju Egungun to ofogun dasọ
Mo juba ki iba mi sẹ o
Ntori mo fẹ sọtọ ta ki i fẹ gbo,
Afo fẹ roko, to ti l a g i si gidi
Sugbọn ẹ ko ni tori gbigbo paja
E ko ni tori kikan pagbo
E ko ma ni tori werewere pobeko
Aiyekotọ o...... o
Igon sore o pa tori
Ntori o sotitọ kun n ni
Akalamagbo sere o yọ gege lorun
Ntori o fotitọ kun n ni
Akukọ Gbangba sotitọ fun kọlọkọlọ
O dẹni nwọn nfi ogbe rẹ tayin
Akukọ fogbe ban kọlọkọlọ
O dẹni nwọn nfi i buta
Aiyekoto o.. ......o!
Bo ba lowo, yana mọ ọ si kun ara rẹ
Bo lọgbọn mọ sikun ara rẹ
Bo lọla, mọ sikun ara rẹ
Ntori baiye ba nfẹ ọ loni
So ngbohun ẹnu mi
Itẹ a nfẹ'na, lọmọ aiye nfẹni
Ba ba lona tan, to ba tiṣe wa lore
A ya domi sori ina
Ka ba rẹbio olore ni
Ntori ifẹ a fadiẹ ko denu, ọmọ Ade
Ṣe ibi kapa a jẹ iomọ
Baiye nfẹ ọ loni
Yara fa ara rẹ leti
Ntori ẹni aiye fẹ, baiye npa
Baiye korira rẹ, bopẹ nwọn a fi ọ silẹ
Ntori o dolosi, oloriburuku alailore-lara
Baiye nfẹ ọ pupọ, waja di ẹru gbogbo nwọn
Ṣaiye ko fẹni fẹrọ, afi ori ẹni
Sugbọn feti bilẹ ko gbọ ọrọ mi
Baiye nfẹ esika, to ntutọ solotọ
Kolotọ ma mu yi iwa pada
Ntori oju-oro, se ni leke omi
Osibata nni nleke odo
Otito ile aiye, on ni nleke irọ
Agabagebe on ni ndi agbelọ-
Boe ngbojuka, baiye nyẹ eke ọmọ Ade
Koloto ma ma pokuuso
Ola lọrun

ORIN (Gbogbo wa la mọ,
(gbogbo wa la mọ
(Ohun se ila lori,
(gbogbo wa la mọ

Ohun to se ila to fi ko lori
To se ikọn to fi wewu eiẹ
Ohun to s'aparo to fi pọn laṣọ
Gbogbo awo lo ye, ko ye ogberi
Sugbọn aiye kotito, irọ laiye nfẹ
Ohun to sọ lagbaja dara le dongo o
Ohun so tamẹda dọrẹ elebiri-po
Ohun sọga dọrẹ onipata

ORIN (Gbogbo wa la mọ,
(gbogbo wa la mọ
(Ohun nṣe nvin, gbo-
(wa la mọ.

### OKU ỌMỌDE KAN FO LOJU OMI NI UMUAHIA

Awọn apeja ri Oku Ọmọ odun medogun kan loju odo Nene leti Abule kan ti nwọn npe ni Ibingou ni Umahia, gbogbo ara re lo ti baje, enia ko si le mo iru enia ti omo na je.

Omo na sonu ninu osu May 10th nigbati awon obi re fe lo si ibi kan ti nwon si ni ki egbon re ma so. Bi igba ti n g b o n egbon omo na ti o si lo yagbe ki o to pada de omo na ti jade lo. Nwon sope awon obinrin meta kan mbe nibe ni i g b a t i omo na di awati. Olopa si nwa idi oro lenu won.




THE WATCH WITH THE PERSONAL TOUCH YOUR PHOTO REPRODUCED ON THE DIAL

REf. N° 55. PHOTO

PRICE £ 5.

WINDSOR


# KERE O! KERE O!!

## CORPULENCE Fat Redusing Tablets

A ṣe awadi egbogi yi fun enyin enia wa ti o lomi lara lọkunrin ati lobinrin lomode ati lagba ni ile Naijiria ogun ara sisan na wa lati iwọ oron Jamani Ajebidan ki gun yi loo e o logan ni ara rẹ yio faye ara sisan ko yẹ ọ iwọ ọmọlọkunrin ati ọmọlobinrin arun buburu ni bi enia ba sanra pupọ ju, ara sisan ju yio mu ọ darugbo lojiji.

Ara sisan ju yio mu o wuwo lori irin.

Ara sisan ju yio mu o buru owo ara sisan ju yio mu ki ọmọlobinrin mase tete loyun ara sisan ju yio mu are ara wa fun iwọ ọmọ lọkunrin lati le sunmọ obinrin.

Teto ra egbogi yi fun lilo re ni kiakia.

Bere lowọ onṣegun adugbo rẹ tabi ni awon ojogbon Onṣegun:-

(1) Champion Chemists 25 Agoro Street Lagos.

(2) Gem Medicine stores Tokunboh Street Lagos.

(3) Cosmopolitan Chemists Strachan Street E.B.

(4) Waterloo Medicine Stores Palm Church Street Lagos

(5) West African Chemists 35 Agarawu Street Lagos.

(6) New Era Chemists 77 Azikwe Street Lagos.

Hassan Commercial Medicine Stores
26 Bishop Street Lagos. Phone 23745

# Nigerian Ports Authority

## VACANCY - HYDROGRAPHIC RECORDER GRADE V

Applications are invited from suitably qualified candidates for appointment to the post of Hydrographic Recorder Grade V in the Harbours Department of the Nigerian Ports Authority.

QUALIFICATIONS:

Candidates should be in possession of the West African School Certificate with credit in Mathematics or the General Certificate of Education at Ordinary Level with passes in at least four subjects including English and Mathematics.

DUTIES:

Successful candidates will be required to assist and write down on all types of hydrographic survey work and take soundings in the launch when sounding. They will also be required to do tracings of hydrographic surveys and carry out monic computations. There will be an initial one year training on these duties and confirmation of the appointments of those selected will depend on individual performances during this training period.

SALARY:

Scale S. £ (4) 143 - 11 - 320/345 per annum (Min. £167).

METHOD OF APPLICATION:

All applications should give full details of age, qualifications and experience, and forwarded to reach the Personnel Manager, Nigerian Ports Authority, P. M. B. 12588, Lagos, not later than 22nd June, 1962. Applicants in Government Departments and Statutory Corporations should forward their applications through their Heads of Departments who are requested to attach Confidential Reports before submitting them.

N. P. A. Notice No. 712.
26th May, 1962.

*BAYO KEHINDE*
*Secretary to the Authority.*

*Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 10, Bamgbose Street P.O. Box 149, Lagos Phone 21953. Glam. E. A. Adenji 94 Oliyide Street, Odu Abore Mushin.*